# Awọn abẹwo si ile-iwe

Itọsọna fun awọn obi ati olutọju

**Kini idi ti Ofsted fi nṣe abẹwo si awọn ile-iwe?**
A ṣe abẹwo si awọn ile-iwe lati pese alaye fun awọn obi, lati ṣe igbega fun ilọsiwaju lati jẹ ki awọn ile-iwe ṣe iṣiro owo ilu ti wọn gba wọle. Awọn abẹwo si ile-iwe jẹ ibeere nipasẹ ofin. A pese iwọn-iye laifarakọ didara ati idiwọn ẹkọ ni awọn ile-iwe, ṣayẹwo boya awọn akẹkọ ṣe aṣeyọri lọpọlọpọ bi wọn ṣe le ṣee.

**Nigbawo ni awọn abẹwo nṣẹlẹ ati bawo ni wọn yoo ṣe pẹ to?**
A nṣe abẹwo si awọn ile-iwe o kere ju ni gbogbo ọdun mẹta sira wọn. Ọpọlọpọ awọn ile-iwe yoo gba akiyesi ọjọ meji ṣaaju ọjọ abẹwo wọn. Abẹwo naa yoo wa fun ọjọ kan tabi meji.

**Tani nṣe awọn abẹwo si awọn ile-iwe?**
Awọn olubẹwo Ọlọla julọ (AỌ) ati Awọn olubẹwo Afikun (AA) ni yoo ṣe awọn abẹwo naa. Gbogbo awọn olubẹwo ni o ti ni ẹkọ si, ati ti ni idojukọ iwọn, awọn idiwọn wa.

**Kini ṣẹlẹ lakoko abẹwo?**
Awọn olubẹwo yoo ka agbeyẹwo-ara ẹni ti ile-iwe ati tu-palẹ awọn abajade akẹkọ ati ilọsiwaju wọn. Wọn yoo ba adari-olukọ, awọn gomina, oṣiṣẹ, ati awọn akẹkọ sọrọ, gbero awọn iwoye rẹ bi obi tabi olutọju. Wọn yoo ṣe akiyesi diẹ ninu awọn ẹkọ ati wo bawo ni didari ati iṣakoso ile-iwe ṣe dara to.

**Bawo ni mo ṣe le jẹ ki awọn iwoye mi di mimọ?**
Ti o ba jẹ obi ti orukọ rẹ wa ninu iwe iranti ile-iwe, ile-iwe naa yoo fi lẹta ranṣẹ si ọ pẹlu iwe iwadi-dẹri lati ọdọ wa. O le sọ fun awọn iwoye rẹ fun wa nipa kikọ si iwe iwadi-dẹri ki o si da pada si ọdọ ẹgbẹ abẹwo ni ile-iwe. Awọn olubẹwo yoo lo awọn iwoye rẹ lati ṣe iranlọwọ fun wọn lati ṣe awọn idajọ wọn. Iwe iwadi-dẹri naa jẹ ohun ilaya, ṣugbọn ti idahun ba jọmọ ariyanjiyan nipa ailewu ọmọde awọn olubẹwo yoo fi alaye naa ranṣẹ siwaju sii.

**Njẹ mo le ba awọn olubẹwo naa sọrọ?**
O le ni aaye lati ba awọn olubẹwo sọrọ lakoko abẹwo, fun apẹẹrẹ, ni ibẹrẹ ọjọ ile-iwe. Awọn alabojuto abẹwo yoo fi idunnu ranṣẹ awọn ifiranṣẹ rẹ si awọn olubẹwo ti o ko ba ni anfani lati ba wọn sọrọ funrararẹ. Awọn alaye bi o ṣe le kan si wọn yoo wa ninu lẹta ti yoo sọ fun ọ nipa abẹwo. Jọwọ ṣe iranti pe awọn olubẹwo ko le ni nkan ṣe nipa aroye to jọmọ ti awọn akẹkọ kọọkan tabi pẹtu si awọn ijiyan laarin iwọ ati ile-iwe naa.

**Kini ṣẹlẹ lẹhin abẹwo naa?**
A yoo fun awọn ile-iwe ni gbogbo ipo lati 1 si 4:

- ipo 1 (dara julọ)
- ipo 2 (dara)
- ipo 3 (kunni loju)
- ipo 4 (aito).

Adari olubẹwo yoo mu awọn ijabọ idajọ lọ si ọdọ adari olukọ ati awọn gomina. Awọn iwari yoo wa ni atẹjade fun ijabọ ile-iwe, awọn obi ati agbegbe to gbooro. Awọn ijabọ olubẹwo ni yoo ṣe iwọn bi iṣẹ ile-iwe ṣe munadoko to ti yoo si ni awọn iṣeduro ninu nipa kinni ile-iwe le ṣe lati mu dara sii. Ile-iwe naa gbọdọ ṣe gbogbo awọn ipele to lẹtọ lati rii daju pe o gba adaakọ ijabọ naa. Ijabọ naa yoo pẹlu lẹta si awọn akẹkọ, ti nsọ fun wọn ohun ti awọn olubẹwo gbero nipa nipa ile-iwe naa ati ohun ti wọn le ṣe lati fun mu dara sii. Awọn ijabọ yoo tun wa ninu atẹjade lori aaye-ayelujara wa: www.ofsted.gov.uk/reports.

**Kini ṣẹlẹ ti Ofsted ba dajọ ile-iwe lati jẹ 'aito'?**
Ti olubẹwo ba dajọ ile-iwe lati jẹ aito yoo wa ni ipo ọkan ninu awọn ẹya meji wọnyi.

Awọn idiwọn pataki
Eyi tumọ sipe ile-iwe naa kuna lati pese fun awọn akẹkọ iwọn itẹnilọrun eto ẹkọ, ko fi agbara han lati ṣe ilọsiwaju ti o nilo. Awọn olubẹwo yoo bẹ ile-iwe naa wo nigbagbogbo lati ṣayẹwo ilọsiwaju rẹ, titi ti o le ṣe yọkuro lati ẹya naa. A yoo tun-bẹwo lẹhin ọdun meji.

Akiyesi lati mu dara sii
Eyi tumọ si ọkan tabi ikeji:
- ile-iwe naa kuna lati pese iwọn itẹnilọrun eto ẹkọ ṣugbọn o ni agbara lati mu dara sii; tabi
- ko kuna, ṣugbọn iṣẹ rẹ ni pataki kere ju ohun ti a nireti to lẹtọ..

Ti a ba gbe akiyesi jade lati mu dara sii, ile-iwe yoo gba ibẹwo alabojuto ni alejo nipasẹ olubẹwo yoo tun-bẹwo lẹhin ọdun kan.

Kini yoo ṣẹlẹ ti Emi ba ni awọn ifiyesi nipa abẹwo naa?
Awọn ifisun ṣọwọn, ṣugbọn a ṣe si wọn ni wiwuwo. O le ṣe iwadi diẹ sii lori aaye-ayelujara wa ni
www.ofsted.gov.uk, tabi nipa pipe laini iranlọwọ wa lori 08456 404045.

Ti o ba nilo alaye eyikeyi diẹ sii nipa iṣẹ wa, jọwọ ṣayẹwo aaye-ayelujara wa tabi pe laini iranlọwọ wa.

Kini yoo ṣẹlẹ ti Emi ba ni awọn ifiyesi nipa ile-iwe ọmọ mi?

Ti o ba ni ifiyesi nipa ile-iwe ọmọ rẹ, o yẹ ki o bẹrẹ nipa sisọrọ taara pẹlu awọn olukọ tabi adari olukọ tabi, ti o ba ṣe dandan, ẹgbẹ ti nṣe iṣakoso tabi alaṣẹ agbegbe. Ti o ko ba ni itẹlọrun pẹlu awọn esi ti o gba Ofsted le ni anfani lati ṣe iranlọwọ.

O le ṣe iwadi diẹ sii lori aaye-ayelujara wa tabi pipe laini iranlọwọ wa.

Alexandra House
33 Kingsway
London WC2B 6SE
Laini iranlọwọ: 08456 404045
**www.ofsted.gov.uk**
Nọmba itọka 070015
© Aṣẹ-lori-ara fadaka 2007

Iwe pelebe yii ntọkasi awọn ile-iwe ti a ti mu duro. Awọn ile-iwe ti a ti mu duro ni wọnyi, pẹlu awọn ile ẹkọ giga ti ṣeto pẹlu owo ilu.